Yoruba يوربا

# 3 Awọn ipin iṣe Ọlọhun lọkan

Ṣiṣe Ọlọhun lọkan (Ọba to tobi) pẹlu ohun ti o jẹ ẹṣa fUN ninu ijẹ Ọlọhun Rẹ, ati jijọsin fUN, ati awọn orukọ Rẹ

Ọna mẹta lo pinsi

### Ṣiṣe Ọlọhun lọkan nibi awọn orukọ Rẹ

Ohun ni ṣiṣe Ọlọhun lọkan (Ọba to tobi) nibi awọn orukọ to so ara Rẹ ati awọn iroyin to fun ara Rẹ ninu Al-Qur'an tabi lati ẹnu ojiṣẹ Rẹ, ki ikẹ ati ọla Ọlọhun ma ba a, iyẹn nipe ohun ti ofi rinlẹ funra Rẹ kia fi rinlẹ fun, ohun ti o sì le jina si ara Rẹ ki a le jina si I, a kò gbọdọ yii pada, tabi ki a paati, tabi ki a wadi pe bawo loṣeri, tabi ki a fi jọ nkan

### Iṣe Ọlọhun lọkan nibi jijọsin fUN

Ohun ni ṣiṣe Ọlọhun lọkan (Ọba to tobi) nibi ijọsin wa tabi nibi awọn iṣẹ awa ẹru Rẹ

### Ṣiṣe Ọlọhun lọkan nibi ijẹ Ọlọhun Rẹ

Ohun ni ṣiṣe Ọlọhun lọkan (Ọba to tobi) nibi awọn iṣe Rẹ tabi ṣiṣe Ọlọhun lọkan (Ọba to tobi) nibi dida ẹda ati ijọba ati iṣakoso

# Awọn ipele ẹsin mẹtẹẹta

## Ṣiṣe daada

Ki o jọsin fun Ọlọhun (Ọba to tobi) gẹgẹ bi ẹnipe o ri I, atipe ti o kò ba ri I, Ohun ri ọ

### Origun kan, ipele meji wa labẹ rẹ

1- Ijọsin riri, ohun ni jijọsin fun Ọlọhun bi ẹnipe o n ri

2- Ijọsin ṣiṣọ, ohun ni pe ti iwọ kò ba ri Ọlọhun, dajudaju Ọlọhun n ri ọ

## Igbagbọ

Ohun ni ọrọ pẹlu ẹnu, igbagbọ pẹlu ọkan, ati iṣẹ pẹlu awọn orikerike ara, igbagbọ ma n lekun, o si ma n dinku

### Awọn opo Igbagbọ 6

1- Igbagbọ ninu Ọlọhun
2- Ati awọn Malaika Rẹ
3- Ati awọn tira Rẹ
4- Ati awọn ojiṣẹ Rẹ
5- Ati ọjọ ikẹyin
6- Oo si gbagbọ ninu kadara, rere rẹ ati aburu rẹ

## Islam

Ohun ni ijuwọjusẹ silẹ fun Ọlọhun (Ọba to tobi) nibi ẹyọkan ṣoṣo Rẹ ati gbigba lati tẹle aṣẹ Rẹ ati bibọpabọṣẹ kuro nibi ẹbọ ati awọn ẹlẹbọ

### Awọn origun Islam: 5

1 Awọn ijẹri mejeeji
2- Gbigbe irun duro
-3 Sisan zakat
-4 Gbigba aawẹ Ramadan
-5 Lilọ si Hajj, iyẹn ẹniti o ba ni agbara lati lọ

# 4 Awọn ipin eewọ:

### Awọn ẹṣẹ kekere

Wọn kere si awọn ẹṣẹ nla) wọn o ma pa ẹṣẹ nla rẹ latara wiwa aforiji, ẹṣẹ kekere yoo di nla latara titẹramọ ọ, Anabi, ki ikẹ ati ọla Ọlọhun ma ba a sọ pe: (Ẹ ṣọra fun awọn ẹṣẹ ti ẹ n foju kere rẹ, nitori pe wọn ma n kojọ sori èniyàn títí tí wọn yóò fi pa á run)

### Awọn ẹṣẹ nla

(Gbogbo ohun ti ijiya kan pato bawa lori rẹ) gẹgẹbi idan, aigbọran si awọn obi mejeeji, owo elé, ṣina, kí ọkunrin ati okunrin ma baraawọn lopọ, irọ́ pípa, mímu ọtí, ole, ọrọ ẹ̀yìn, pipa eniyan ti Ọlọhun ṣe leewọ ayafi pẹlu ẹtọ, Jijẹ owo ọmọ-orukan

### Ẹbọ kekere

(Koni yọni kuro ninu ẹsin, o tobi ju awọn ẹṣẹ nla lọ) gẹgẹbi sisọ pé: "bi Ọlọhun bafẹ ti iwọ naa fẹ", Ibura pẹlu nkan to yatọ si Ọlọhun, kárími diẹ, paro ẹlẹbọ, ríro nkan ti kòdara, siso ìlẹ̀kẹ̀ kọ́, ati bẹẹ bẹẹ, lori pé okunfa iṣọ ni wọ́n jẹ́ tabi pe wọ́n ma ti awọn ajẹ danu

### Ẹbọ nla

(O n yọni kuro ninu ẹsin, wọn kò ni foriji i ti o ba ku sori rẹ) o fun Ọlọhun ni orogun, ti o n pe e gẹgẹbi o ti n pe Ọlọhun, tabi o n bẹru rẹ, tabi o n rokàn si ọdọ rẹ, tabi o n nifẹ rẹ gẹgẹbi ifẹ Ọlọhun, tabi o n ṣe ijọsin kan ninu awọn ijọsin fun